# EWU NLA LO LORI AZIKIWE, EWU LO!



SEE YOU PAY THE CORRECT PRICE.

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO



AWOGBA
Omode fun Girl, Eyl, Hihu-ehin, Orere.
Ra Tire Ni Ile Egbogi
— ISE —
Olodun are Okebola, Ibadan.
116, Great Bridge St LAGOS

VOL. No. IX 516. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, APRIL 20, 1957 KOBO MEJI (2d

## Ewu Lo Lori Azikiwe

Ni ọjọ Atalata ọjọ 16th oṣu April 1957, nigbati awọn aṣiwaju ilẹ wa mẹtẹta lọ ṣe ipade ninu ile Gomina nilu Eko.

A gbọ pe nṣe ni awọn ero iworan ti, nwọn si pọ bi omi. Nigbati moto Azikiwe de, bẹni ọdọmọkunrin kan sare tẹle mọto rẹ lẹhin pẹlu ọbẹ ti o fa yọ.

Ṣamọṣamọ ọkunrin yi ti lugọ de Azikiwe bi mọto rẹ ti yọ nṣe ni ọkunrin na ju okuta lu jigin mọto rẹ ki o to wa fa ọbẹ yọ. Ọkunrin kan ti a npe ni Amechi akọwe ẹgbẹ Alakukọ ni Ila Orun, lo kọkọ sọlu ọkunrin buruku na ki awọn ọlọpa to wa ki mọlẹ, nwọn gba ọbẹ ọwọ rẹ, nwọn si mulọ si itimọle.

Bi a ti mọ ọkunrin na si ni pe Pius Kaine ni orukọ rẹ njẹ, o si jẹ aburo fun Lọya Kaine, a gbọ pe ọkunrin na ti lọ kọ iṣẹ Lọya ri ni ilu Oyinbo, ṣugbọn nṣe ni ijọba da pada wa sile nitoripe ko si ilera fun.

Nisisiyi awọn ọlọpa ti mura lati ba eni na ṣe ẹjọ wipe, o gbindanwo lati pa enia.



DR. NNAMDI AZIKIWE

## Okunrin na niyi



Ọkunrin kan ti a sọ wipe o nfẹ gun Dr. Azikiwe lọbẹ nigbati o wa fun ọrọ ajọsọ ni ilu Eko, ni a nwo ninu aworan yi ti awọn ọlọpa ramu papankoko yi, orukọ rẹ ni Pius Kaine

**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital – £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria.
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS, NIGERIA
22 Branches throughout Nigeria including IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY, WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell
Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams: Natbaniger, London.
Head Office Representative in London
Ernest Olubunmi Obasa—Porter
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG

## Oloye Obafemi Awolowo



Eniti a nwo ninu aworan ni Oloye Obafemi

Awolọwọ ti o nṣe Prime Minister fun ijọba Iwọ-Orun, ilẹ Nigeria, on yi kanna ni aṣiwaju ẹgbẹ Action Group. On ni eniti ọrọ rẹ wọ eti Azikiwe ati Sardauna Ṣokoto tobẹ ti a gbọ pe, ọrọ wọn papọ, nwọn si fi ohun ṣọkan lati gba ominira ilẹ Nigeria lasiko kanna-1959.



# ELETI ỌFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kosoko Street, Lagos P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAM "ELETI - ỌFE LAGOS" Phone 23370

VOL. IX. NO. 516, LAGOS, SATURDAY APRIL 20, 1957


## Omo eni ni ijogun eni

Ọrọ yẹpẹrẹ kọ ni ọrọ ọmọ bibi fun awa ẹda enia ni gbogbo Orilẹ-ede to wa labẹ ọrun papa fun awa Yoruba, o si jẹ ohun ti kole ṣai ṣe ribiribi fun ijọba ki ijọba nitoripe bi ko ba si enia, ibaṣe ọkunrin tabi obinrin nilu o ṣoro ki inu ijọba ilu bẹ to le dun nitoripe enia ni ijọba njọba le lori ki iṣe ẹranko tabi igi ati ọpẹ.

Gẹgẹbi iwa A-do-nkia (I don't care) ati iwa agbere ti wọpọ to nilu Oyinbo sibẹsibẹ ọgọrọ aimoye Oyinbo mbẹ nibẹ ti ọrọ ọmọ jẹ ẹdun ọkan wọn, a tilẹ le ri baba tabi iya miran ti nwọn ko kọ lati fi ẹmi wọn le'lẹ fun ọmọ wọn bi ọrọ ba di karangida.

Melomelo ni a ṣẹṣẹ le sọ ni ti awa enia dudu ti a ki ko iyan ọmọ-ninu kere: nitotọ, owo le jẹ ẹgbọn ki ọmọ jẹ aburo ṣugbọn, olowo enia miran mbẹ ti o jẹ wipe Ẹbun Ọlọrun ti ko si lori atẹ ita'ja yi sọwọn fun, ti nwọn ko si kọ lati bana gbogbo dukia owo irọn na lati wa nipo ẹniti a le bere pe ara ọmọde kele bi ẹ ? tani irufẹ ibere ifẹ bayi ki wu ninu awọn obinrin?

Ọmọ iye, ọrọ ọmọ ko ri bẹ ! ki Edumare ma ṣai fun ni niti aefani, ọrọ̀ọmọ tete fun ni !! ọrọ ọmọ janto-janto !!!

## River Class Engine



Ẹrọ reluwe ti a nwo yi jẹ ẹya iru awọn ayara ti aṣa ti awọn olotu iṣẹ Reluwe ranṣẹ fun lati fi ko awọn ẹru ẹpa to sọjọ silu Kano, a si gbọ pe awọn ẹru ẹpa na ti o dabi oke nigbero ilu Kano na ni nwọn ti ko tan. Ọkọ ti o ṣubu ni Teṣọn Agege jẹ ẹya iru ọkọ yi ṣugbọn nwọn ti gbe dide nisisiyi, o ti nṣiṣẹ.

## Bale awon Onigbagbo Salaisi

ABẸOKUTA. Anu ṣe ni jọjọ lati jihin iku Oloye James Popoọla Ladeinde, ti o aṣe Balẹ awọn Onigbagbọ ti Ago Oko ni agbole Ẹlẹmọna ni Abeokuta.

A gbọ wipe alagba J. P. Ladẹinde yi je ọkan pataki ninu awọn agba Ogboni ti o nṣe igbimọ fun ilọsiwaju ilu Egba.

A gbọ wipe Ologbe yi di ẹni ọdun mẹtalelọgorin nigbati o fi aiye sile. Awọn ti o je pataki ninu ọmọ rẹ ni Ọgbẹni A O. Ladẹinde, J. N. O. Ladẹinde, E. O. Ladẹinde, Iyafin J. O. Soge ti ilu Ọffa, Iya- V. O. Dailey ti ilu Ibadan ati Iyafin F. O. Oshoi.

Ki Oluwa dẹ'lẹ fun u.

## Ofin Igba Lailia Ni Amerika

Nigba lailai nilẹ Amẹrika ninu ilu kan ti nwọn npe ni Pẹnsil-fania (Pensylvania) lasiko ti mọtọ koiti wọpọ to bayi, nwọn ṣe ofin kan fun awọn oni-moto bayi wipe:-

Awọn agbẹ, ti ko ni mọto, ti nwọn ko si fẹ ki a lo ẹrọ mọto larin ilu, awọn lo ṣe ofin yi, nitoripe, awọn lo pọju ninu igbimọ. Nwọn ni gbogbo awọn mọto ti o ba lọ si ọna oko ni oru, ni lati ma tan ina iwaju mọto ni baṣẹ kọkan nitoripe lasiko na, mọto ko ntan ina siwaju loru.

Bi moto na ba tan ina yi tan, o ni lati duro fun iṣẹju mẹta pẹlu ina titan ki o to tun ma lọ. Bi o ba si ti nrin lọ beni ki o ma fẹn fere rẹ.

A ti wipe nigbati ẹṣin ti o nwọ kẹkẹ ẹlẹṣin kan ba taku lati sọda oju ọna mọto, ki baba ẹlẹṣin na sọkalẹ ki o tu kẹkẹ kuro lara ẹṣin na, ki o si lẹ fi kẹkẹ na pamọ sinu gbo kan ki ẹṣi maṣe ri.

Gbogbo eyiti a wi yi je ofin ti nwọn nilẹ Amẹrika ninu ọdun 1900 nigbati kẹkẹ ẹlẹṣin pọ ju mọto lọ. Ṣugbọn nisisiyi, awọn ofin nwonyi ti pada, nitori aiye ti di aiye mọto, diẹ ni awọn kẹkẹ ẹlẹṣin ti o tun ku nile aiye.

## Eran Obo Ko Iba Ponju-ponju Wolu

Nilu kan nilẹ Amẹrika arun Iba Pọnju-pọn (Yellow Fever) papọju nilu na, tobẹ ni igbati awọn Dokita dide si, nwọn ṣẹgun arun na nwọn si pana rẹ patapata kuro larin enia. Nigbati arun yi ko sinu igbẹ, o lọ kẹtu awọn ọbọ, lagido pọnwọla, aaya, ẹdun, ati iji mere, arunyi bẹrẹ si yọ awọn awọn ọbọ nwọnyi lẹnu tobẹ ti nwọn bẹrẹ si ja lulẹ lati ori igi. Nigbati awọn enia ba ri awọn ọbọ nwọnyi, nwọn o lu pa, nwọn o si gbe lọ sile lo se jẹ. Ni ṣiṣe bayi, arun ti awọn Dokita ti le wọ igbẹ tun npada si ara awọn enia larin ilu.

Bi ọrọ na ti lọ niyi. Ni ọdun 1948 nilu Panama (City) ni nwọn tun gbe awọn enia marun wa sile iwosan ti o ni iru arun buraku Iba Pọnju-pọnju yi. o jẹ ohun iyanu fun awọn Dokita wipe ohun ti awọn ti panọ rẹ l'ọdun 1906 bawo lo ṣe tun dide ni ọdun 1948?

Nwọn bẹrẹ si ṣe iwadi firi firi, ninu iwadi yi ni awọn ti ri wipe awọn ti o njẹ ẹran ọbọ ti arun iba pọnjupọnju ko jẹki awọn tun le rin lori igi ti awọn enia si lupa ti nwọn gbe wale wajẹ, lo ko arun na wọlu.

Ṣugbọn lọtọ yi, gbogbo ilu Panama City, Panama Canal, Western Panama, Costa Rika, Nikaragua ati British Honduras ni arun iba na yọnu, a si gbọ pe awọn Dọkita ti dide si lati panọ rẹ.

## Oba Ilorin Si Igbimo Kotu Offa

Lehin ti Ọba Ilọrin ti tilekun kotu Ọffa nitori ede ko yede ti o mbe larin Ṣehu Abudul Kadiri Ọba Ilọrin ati Isioye ọba, ọba Ọlọfa ilu Ọffa, ni awọn ijọba ibile tun pada wa ṣi kotu na ni Malam Sulu Gambein.

Ọba Ilọrin ko gba ki Isioye ṣe oleri ninu igbimọ na, eniti nwọn fi ṣe e si esa ilu Ọffa nwọn si tun yan Onira lati ma wa joko ṣe Kotu pelu awọn ara Ọffa

# Rogbodiyan Algeria di wo si Faranse lorun

Rogbodiyan ijagboro to bẹ silẹ nilu Moroko, on kanna lo gberan titi de Tunis ati Algeria, a si gbọ pe nṣe ni awọn ara Algeria di egungun to ha Faranse lọrun. Nisisiyi awọn Faranse nfẹ ki ija na pari, ṣugbọn awọn ilu Algeria taku wọnle.

Awọn agbagba ilẹ Algeria ni awọn ijọba Faranse ranṣẹ pe wipe, ki awọn ranṣẹ pe awọn enia wọn ki nwọn da rogbodiyan gbogbo duro, ki nwọn gbọ ọrọ ti ijọba yio ba wọn sọ.

Irohin sọ fun wa wipe, ogun awọn ara ilẹ Algeria ti ka ogun ọkẹ mọ ninu ọmọ ogun ilẹ Faranse tobẹ ti awọn ko le lọ siwaju tabi si ẹhin.

Awọn Larubawa lo ni ilu na, nwọn ranṣẹ pada si Faranse wipe, bi ẹru ba pẹ nile, yio di ọmọ, ko si ohun ti o le si awọn ni ipo pada nibiti nwọn wa, ayafi ki Faranse fun awọn ni Ominira na.

A koiti mọ igbẹhin ma fẹ mi niṣo.

# Ibunkun ni Iranti Olododo



T. ỌMỌṢỌLA SAVAGE

O di odun kan nisisiyi ti o ti file bora bi aso, Oloye Are ilu Eko, Awa kole gbagbe inu rere re si omode, si agbalagba, si onile ati alejo.

Sunre! sunre!! sunre!!!

# Onisegun Fun Egbe Reluwe

Ọgbẹni Dokita Edmund Nathaniel Oyekanmi Ṣodẹinde ni ẹniti awọn igbimọ Reluwe yan gẹgẹbi ẹnikini ninu awọn enia dudu lati ma ṣe iṣẹ iṣegun larin awọn oṣiṣẹ Reluwe na, ki o si ma wa ọna imọtoto larin awọn oṣiṣẹ na ati kakiri ibugbe wọn. Ẹniti o jẹ ọga agba fun Dokita na ni Dokita John Dryden.

Dokita Ṣodẹinde jẹ ẹniti o ti ṣe iṣẹ labẹ ijọba ri, ninu ipo giga lo si wa lasiko na. Nigbati o dagba di ọmọ ọdun mẹtadilogun lo gba isinmi kuro lẹnu iṣẹ. Ninu ọdun 1939 lo pega ninu iṣẹ yi, ti o si gba oye nwọnyi, M. A., M. D., B. Ch., B. A. O., ati L. M.

Dokin Ṣodẹinde lo ma ki ọsẹ ilere di nimọ ati ohun pataki ni iha Ila-Orun ati Iwọ-Orun nipa aayan ati igbiyanju rẹ ti o ma nṣe alaye fun awọn enia nipa alafia ati ilera ara enia. O ti ṣiṣẹ Iṣegun ti Oyinbo ni awọn ipinlẹ meteia, ni Ila-Orun, Iwọ-Orun, ati ni iha Ariwa. Ọba Obinrin fi Medali ti ọjẹ igbade rẹ da lọla, ni ọdun 1953 bakanna lo si tun gba oye M. B. E ni ọdun 1956.

# Oba Adele Sure Fun Awon Asiwaju Wa.

Nigbati awọn asiwaju ilẹ wa mẹtẹta de si ilu Eko, Alaiyeluwa Ọba Adele keji lo kọkọ gba wọn ni alejo. Iwọnyi ni awọn ọrọ ti ọba na sọ, ti o fi ki wọn, ti o si fi sure fun wọn.

Ipo mi, gẹgẹbi ọba ilu Eko ati gẹgẹbi baba igbimọ Lagos Town Council, mo fi tọkan-tọkan ki awọn aṣiwaju mẹtẹta wipe, ki nwọn ma wo'le, ki nwọn ma rọra. Bakanna ni awọn ijoye mi ati awọn ara Eko ki wọn ni ma wolẹ, ma rọra, ki Ọlọrun br wọn lọwọ sinu eto rere ti awọn fẹ ṣe.

Mo mọ pe iṣọ ti o wa aiwaju wọn ṣore jọjọ, ṣugbọn pẹlu agbara Olodumare, pẹlu ọkan iyọnda fun ara ẹni, ọrọ wọn na yio papọ si rere fun anfani gbogbo enia ilẹ wa, yi o si jẹ iyin ati ogo fun awọn aṣiwaju wa na.

Ẹnyin aṣiwaju wa, mo fi nyin si abẹ iṣọ Ọlọrun, ki Ọlọrun pẹlu nyin.


# Kere o!

A ti ni oriṣiriṣi ogun German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Yete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.



HINDU SANKARA'S

Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawaches, Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries

*Enclose [illegible] money order by Air Mail for Catalogues and Literature.*

HINDU SANKARA, 20 Muntpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England


# Ada Egbe omo Oke-Eletu Sile

Ni ọjọ Ọsẹ ti o kọja ti Iṣe ọjọ keje Oṣu kẹrin ni ọdun yi ni a fi idi ọmọ Ẹgbẹ Oke-Eletu yi Mulẹ Gbogbo awọn agba gba ilu na ni wọn gba fi ara mọ iru Ẹgbẹ ti awọn ọmọ ilu wọn da sile yi. OLOTU ijoko na ni ELETU of OKE-ELETU, BALẸ ILU Ati AJANỌ of OKE-ELETU-ALAṢẸ.

Wọn ṣe eto gẹgẹ bi ilu wọn yio ṣe ma dara ati awọn abule kekere agbegbe wọn ṣe ma ni irẹ pọ larin ara wọn lai si ija tabi aṣọ. Aṣoju awọn Ẹgbẹ na ni Y. A. Oyenuga K. Oṣikoya A. Ọla Bello L. S. Odus C. A. Bogunde W. Ṣeyọmbọ B. Banjoko Thompson Arewole Y. S. Alakọ ati J. Ọrẹnuga ati awọn bẹbẹ ti akole darukọ wọn nisisiyi.

# Shetima Kashim



Eniti a nwo yi ni Malam Shetima Kashim okan ninu awọn asiwaju ile Hausa ti o ti gba oye nia M.B.E., M.H.R. on ẹniti o lo si igbimo Cambridge ti o si pada wa je abo lori ero gbohun-gbohun ti N.B.C.




## ARADAN NERVIGORA

Ogun ẹjẹ pataki fun imarale agba ati arẹmọ pipe fun awọn alaya pupọ. O dara fun inarun; ẹjẹ didu, iṣokun oju, gbigbọn ọwọ, ailesun, ailokun ninu, ati irufẹ arun bawọnni. O jẹ ajidewe fun awọn ti agbara wọn ndinku. On na ni, ọkunrin yi lo ti o fi di "Afẹṣẹ kun b ojo." 5/6d. pere pẹlu owo ọkọ 1/6d e.g. 7/- Post Free.

**The Egba Trading Aradan Stores** 112, Denton Street, 18, Denton Bridge Street, P. O. Box 2. Ebute-Metta. Phone 44153. A tun wa ni New Motor Park (Ogunpa) Ibadan.


No 56

## Department of Posts And Telegraphs

### SECOND C[illegible] AIR MAIL SERVICE

It is noti[illegible] general information that the SECOND CLASS AIRM[illegible]RVICE has been extended to include all countries in [illegible]ROPE, and the UNITED STATES OF AMERICA.

POSTAGE RATES

| | |
|---|---|
| EUROPE ... ... — ... | 6d per 1/2 oz. |
| UNITED STATES OF AMERICA | 7d per 1/2 oz. |

Second class mail matter consists of Printed papers, Commercial papers, Samples, Small Packets, and Articles and Literature for the Blind Information regarding the limits of weight and size may be obtained from all Post Office and Postal Agencies.

H. O. ELLIS
Director of Posts and Telegraphs.

## Sardauna Sokoto



**Alhabji Ahmedu, ti o nse Sardauna Sokoto je okan ninu awon Ogunna gbomgbo meta ile Nigeria ti nwon lo soro pataki ninu ile Gomina agba nilu Eko. Oro re papo mo ti awon yoku.**

## ISIMI ỌDUN IMALE

**Gegebi o ti je wipe asiko ti nwon ise odun Awe nile Yoruba ati Ila-orun ki idogba pelu ti ipinle Oke-Oya, nitorina ni Gomina agba se fi ase si awon ojo odun na bayi:-**

**Ni ipinle Yoruba ati Ibo, ojo kini osu May,** 1957 ni nwọn fẹ kirun ọdun tiwọn.

**Nitorina Gomina agba fi ase si bayi pe ki 30th osu April, je isimi ti enikeni ko ni sise, lati ba awon Imale yo ayo odun kekere kakiri ile Oke-Oya. Sugbon ojo 1st May, 1957 ni ojo ti nwon ni o kirun nile Yoruba, ati Ijoba** ati Oniṣowo, ẹnikan ko gbọdọ ṣiṣẹ, ki ọjọ na jẹ ọjọ isimi fun gbogbogbo.

## Queen's Birthday Parade Lagos 1957

His Excellency the Governor-General, Sir James Robertson, G. C. V. O., K. C. M. G., K. B. E. will attend the ceremonial parade which will take place on the Lagos Race Course at 7.50 a. m. on Tuesday the 23rd of April, 1957, in celebration of the Official Birthday of Her Majesty Queen Elizabeth II.

This is to be a joint parade by the Nigerian Military Forces and the Nigeria Police, and the troops taking part include the Headpuaters, Southern Sub-District, the 2nd Battalion the Queen's Own Nigeria Regiment, the Nigeria Police, and the massed bands of the Queen's Own Nigeria Regiment and the Nigeria Police, together with the two Corps of Drums. The parade will be commanded by Brigadier M. R. Lonsdale, D. S. O., O. B. E.

All seats in His Excellency's Box, the Prince of Wales Stand and the Grand Stand will be reserved for members of the Council of Ministers, officials and leading members of the public, to whom invitations will be sent. Admission to these seats will be by ticket only.

All those without tickets will be accommondated round the ropes enclosing the parade ground.

Officials attending the ceremony who are entitled to wear uniforms should do so. Civilians are requested to wear the medals to which they are entitled. All spectators must be in their places by 7.30 a.m. The Nigerian Broadcasting Corporation is making arrangments to broadcast the ceremony.

The attention of all car owners is drawn to the following traffic arrangements:-

(1) Between 7 a.m. and 9 a.m. Racecourse Road between Moloney Street and the Junction of Onikan Road with Force Road will be closed to traffic.

(2) Between 7 a.m. and 9 a.m. the road leading towards the Grand Stand from the junction of Onikan Road with Force Road will be closed to traffic going in the direction of the Colonial Church.

(3) The only approach to the Stands will be from the direction of the Colonial Church.

Arrival: There will be three Car Parks:-

Park A Race Course Paddock, with overflow (if necessary) on to the road leading from the Grand Stand to Force Road. This park is for use by vehicles which have an Orange coloured label affixed to the windscreen;

Park B on the Race Course, opposite the Colonial Church with overflow (if necessary) in Campbell Street. This park is for use by vehicles which have a Green car label affixed to the windscreen;

Park C on the Children's Playground opposite King's College. This park is for use by vehicles which have no car label.

Departure: Vehicles from Park A will leave via Force or Paddock Roads: Vehicles from Park B will leave via Cable Street, Broad Street or King's College Road. Vehicles from Park C will leave via Catholic Mission Street. General Advice. To assist the Police and to avoid unnecessary delay, holders of orange and green car labels are requested to affix the label on the left (near) side of the windscreen of their vehicles.

Invitations to the press and to photographers are being issued by the Chief Administrative Officer, Lagos.

In the event of bad weather necessitating the cancellation of the Parade, the Nigerian Broadcasting Corporation will make regular announcements of the cancellation on their programmes starting at 6.45 a.m.

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company. 28, Kosoko Street P. Box O. 467 Lagos Phone 23578